ÈDÈ YORÙBÁ · YORUBA

# Irinṣẹ́ Àgbègbè Ìpínlẹ̀ New York

Ìtọ́sọ́nà ohun èlò fún àwọn aṣíkiri Ará New York

Oṣù Keje Ọdún 2026



**New York Immigration Coalition**
nyic.org

Àgbáríjọ Àjọ Ìwọlé-jáde New York ṣe àgbékalẹ̀ irinṣẹ́ yìí láti pèsè ohun èlò fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè àti àwọn alábàáṣiṣẹ́pọ̀ wa àti àwọn alájọṣepọ̀ wa tí wọ́n ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú wọn. Irinṣẹ́ yìí máa ń wà ní ìmúdójúìwọn nígbàgbogbo dá lórí ìyípadà àwọn òfin àti ìlànà.

Imudojuiwọn to kẹhin: 7.31.26

**Atọ́ka àkóónú**


- Ìkìlọ fún Àwùjọ **3**
- Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ **6**
- Ìlera **10**
- Àwọn ilé-ìwé àti ẹ̀kọ́ **13**
- Àábò Àgbègbè **16**
- Àwọn ohun àmúlò iṣẹ́ NYS **17**

# Ìkìlọ fún Àwùjọ

## Ìyọkúrò Ní Ìyára

### Trump ṣe Ìmúgbòòrò "Ìyọkúrò Ní Ìyára" láti Lé Àwọn Olùsíwọ̀lú Kúrò Nílùú Kíákíá

- Ilé-ẹjọ́ ìjọba àpapọ̀ kan ti gba Ìjọba Trump láàyè láti fẹ ojú ètò "ìyọkúrò ní ìyára" láti lè yọ àwọn olùṣíwọ̀lú kúrò nílùú láì rí adájọ́ tó ń bójú tó ọ̀ràn ìṣíwọ̀lú.
- Àwọn olùṣíwọ̀lú tí kò ní ìwé àṣẹ ní ibikíbi ní Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà tí kò sì leè fi ẹ̀rí hàn pé wọ́n ti wà nílùú fún ọdún 2 báyìí lè di ẹni tí wọ́n máa lé kúrò nílùú ní kíákíá.

### Ẹni tó wà nínú ewu èyí jùlọ?

- Bí kò bá tíì tó ọdún 2 sẹ́yìn tí o dé sí Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà tí DHS sì fi ọ́ sí àtìmọ́lé, o lè wà ní ewu lílé kúrò nílùú ní kíákíá. Ìgbésẹ̀ yìí ni a ń pè ní ìyọkúrò ní ìyára.
- O lè wà ní ewu rẹ̀ tí:
  - O dé sí Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ní kò tó ọdún 2 sẹ́yìn àti
  - O wọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà láìsí àyẹ̀wò (nípasẹ̀ ibodè tó wà láàárín àwọn èbúté ìwọlé), nípasẹ̀ ètò ìgbélùú fún ìgbà díẹ̀ bíi àṣẹ ìgbélùú onígbà díẹ̀ ti CHNV, tàbí lílo CBP One App.

### Báwo ni mo ṣe lè dáàbò bo ara mi?

- Tí o bá ti wà ní Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ju ọdun 2 lọ, o yẹ kí o máa ní ẹrí ìgbé nílùú pẹ̀lú rẹ, bíi ìwé ìyálé-gbé tàbí ìwé ìsanwó ohunèlo ilé tó bo àkókò yìí.
- Tọju àwọn ẹ̀dà ìwé ẹ̀rí ìgbélùú rẹ sílé àti/tàbí pẹ̀lú ẹnìkan tí o lè gbẹ́kẹ̀lé bíi ọ̀rẹ́ kan, mọ̀lẹ́bí, tàbí agbẹjọ́rọ̀.
- Tí o bá ní àmúyẹ, rí i dájú pé o ti forúkọsílẹ̀ fún ètò ibi ìsádi tàbí fún àwọn ìbẹ̀wẹ̀ mìíràn pẹ̀lú Ilé-ẹjọ́ Ìṣíwọ̀lú tàbí USCIS, kí o sì ní ẹ̀rí àwọn ìbẹ̀wẹ̀ tí o forúkosílẹ̀ fún.
- O lè pe Ọ́fíìsì NYS fún Aago Ìpe Pàjáwìrì Àwọn Aráàlú Amẹ́ríkà Tuntun ní 1-800-566-7636 fún àwọn ìbéèrè àti àbá nípa ibi tí o ti lè gba ìmọ̀ràn nípa òfin lórí ìṣíwọ̀lú.

### Báwo ni mo ṣe lè múra sílẹ̀ fún ìṣeèṣe àtìmọ́lé?

- Múra sílẹ̀ kí o sì ṣètò ètò ààbò pẹ̀lú ẹbí tàbí àwọn ará àwùjọ rẹ bí ó bá ṣẹlẹ̀ pé wọ́n fi ọ́ sí àtìmọ́lé.
- Darapọ̀ mọ́ àwọn ìjọ ìtìlẹyìn ti ilé-ẹjọ́ tàbí ní ẹnìkan tí yóò tẹ̀lé ọ lọ sí ilé-ẹjọ́ tàbí àwọn ìpàdé pẹ̀lú DHS.
- Tí wọ́n bá fi ọ́ sí àtìmọ́lé tí o sì ń bẹ̀rù láti padà sí orílẹ̀-èdè rẹ àti/tàbí orílẹ̀-èdè míràn, sọ èyí kedere fún ICE àti àwọn òṣìṣẹ́ tó ń rí sí ọ̀ràn ìṣíwọ̀lú, o lè ní láti ṣe èyí ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà. Kódà bí o bá ti ṣe ìbẹ̀wẹ̀ fún ibi-ìsádi tẹ́lẹ̀, ó yẹ kí o tún ṣàlàyé ìbẹ̀rù rẹ fún ìfòòró ẹni tàbí ìfiyàjẹni lẹ́ẹ̀kan síi.

# Ìkìlọ fún Àwùjọ

## Àwọn Ìfòpin sí TPS

### Ìdájọ́ Ilé-ẹjọ́ Gíga Jùlọ fòpin sí TPS fún Haiti and Syria

- Ní 25 Oṣù Kẹfà, Ọdún 2026, Ilé-ẹjọ́ Gíga Jùlọ ti Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ṣe ìdájọ́ tó gba Ìjọba Trump láàyè láti fòpin sí ètò Ipò Ààbò Onígbà Díẹ̀ (TPS) fún Haiti àti Syria.
- Àwọn Aráàlú New York tó pọ̀ ju 40,000 lọ máa tó pàdánù àwọn ààbò òfin tí wọ́n sì wà ní ewu àtìmọ́lé àti lílé kúrò nílùú. Ìdájọ́ yìí tún jé kó rọrùn fún Ìjọba Trump láti fòpin sí ipò TPS àwọn orílẹ̀-èdè míràn ní ọjọ́ iwájú.

### Kíni èyí túmọ̀ sí àti kí ni ó kàn tí yóò ṣẹlẹ̀?

- Àwọn Aráàlú Haiti àti Syria tí wọ́n ní ipò TPS máa tó pàdánù agbára wọn láti gbé tàbí ṣiṣẹ́ pẹ̀lú ìwé àṣẹ ní Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà.
- Ìdájọ́ Ilé-ẹjọ́ Gíga Jùlọ wà ní ìṣètò láti bẹ̀rẹ̀ síi ní ipa lọ́jọ́ 27 Oṣù Keje, Ọdún 2026, àyàfi tí àwọn àṣẹ mìíràn bá wá láti ilé-ẹjọ́. Wọ́n retí kí Ẹ̀ka Ìṣàkóso Ààbò Ìlú (DHS) gbé ìgbésẹ̀ síwájú síi láti fòpin sí TPS fún Haiti àti Syria láìpẹ́. Wo uscis.gov/TPS fún àwọn ìmúdójúìwọ̀n.
- Bí ìdájọ́ yìí bá kàn ọ́, má fòyà! Gbé ìgbésẹ̀ nísìnyí láti dáàbò bo ara rẹ àti ẹbí rẹ.

### Báwo ni mo ṣe lè dáàbò bò ara mi?

- Tí o bá ní TPS lọ́wọ́lọ́wọ́:
  - Bá agbẹjọ́rò ìṣíwọ̀lú tó ṣe gbẹ́kẹ̀lé tàbí àwọn aṣojú tí òfin fọwọ́ sí sọ̀rọ̀ ní kíákíá láti mọ àwọn àsàyàn tí o ní. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn tó ní TPS lè ní àwọn ọ̀nà míràn lárọ̀wọ́tó, tó fi mọ́ àwọn ọ̀nà tó dá lórí mọ̀lẹ́bí àti iṣẹ́.
    - Ṣọ́ra fún àwọn afàwọ̀rajà, àwọn agbẹjọ́rò èké, àti ẹnikẹ́ni tó bá ń ṣèlérí àwọn àǹfààní ìṣíwọ̀lú tó dájú!
  - Má ṣe kúrò ní Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà láì gba ìmọ̀ràn nípa òfin. Tí o bá pinnu láti kúrò, wọ́n lè ka pe o ti kọ àwọn ìbẹ̀wẹ̀ tí o forúkọsílẹ̀ fún sílẹ̀ àti kí a ma jé kí o wọlé sí Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà mọ́ lọ́jọ́ iwájú.
  - Múra sílẹ̀ kí o sì ṣe ètò ààbò pẹ̀lú ẹbí tàbí àwọn ara àwùjọ rẹ bí ó bá ṣẹlẹ̀ pé wọ́n fi ọ́ sí àtìmọ́lé.
  - Mọ Awọn Ẹ̀tọ́ Rẹ! Tí ICE bá wa ọ wá, o ní ẹ̀tọ́ láti má sọ̀rọ̀. O lè kọ̀ láti jé kí wọ́n wọlé láì pèsè àṣẹ adájọ́.
  - Tí ICE bá mú ọ, o gbọdọ̀ sọ fún àwọn òṣìṣẹ́ náà lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ tí ẹ̀rù bá ń bà ọ́ láti padà sí orílẹ̀-èdè rẹ àti/tàbí orílẹ̀-èdè míràn. O lè ní láti tún un sọ fún àwọn òṣìṣẹ́ tó ń rí sí ọ̀ràn ìṣíwọ̀lú pé ò ń fẹ́ ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò ìṣeégbàgbọ fún ìbẹ̀rù àti àǹfààní láti béèrè fún ibi-ìsádi.

### Àwọn Ohun-èlo

- Láti gba ìsọfúnni àti àwọn ìtọ́kasí fún ìrànlọ́wọ́ ofin, pe Ọ́fììsì NYS fún Aago Ìpe Pàjáwìrì Àwọn Aráàlú Amẹ́ríkà Tuntun ní 1-800-566-7636
- Àwọn olùgbé Ìlú New York tún lè pe Aago Ìpe Pàjáwìrì Ìrànlọ́wọ́ Òfin Ìṣíwọ̀lú ní 1-800-354-0365, tàbí pe 311 kí o sì sọ pé "Òfin Ìṣíwọ̀lú "
- Láti rí àtòjọ àwọn olùpèsè iṣẹ́ òfin nípa ọ̀ràn ìṣíwọ̀lú ní ọ̀fẹ́ tàbí ní owó pọ́ọ́kú káàkiri orílẹ̀-èdè, kàn sí visit www.immigrationadvocates.org/legaldirectory

# Ìkìlọ̀ fún Àwùjọ

## Ìṣètò Àwọn Ìgbẹ́jọ́ Àpapọ̀ Olùjẹ́jọ́

### Àwọn Ilé-ẹjọ́ tó ń rí sí Ọ̀ràn Ìṣíwọ̀lú Ṣètò "Ìṣètò Àwọn Ìgbẹ́jọ́ Àpapọ̀ Olùjẹ́jọ́"

- "Ìṣètò Àwọn Ìgbẹ́jọ́ Àpapọ̀ Olùjẹ́jọ́" jẹ́ ìgbẹ́jọ́ kan tí wọ́n ṣètò fún èèyàn 100 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ lẹ́ẹ̀kan náà, tó dìídì dojú kọ àwọn èèyàn tí kò ní agbẹjọ́rò tó ń ṣojú fún won. Fún àwọn ọ̀pọ̀lọpọ̀ olùṣíwọ̀lú, ìgbẹ́jọ́ àpapọ̀ olùjẹ́jọ́ ni ìgbà àkọ́kọ́ wọn ní iwájú adájọ́ tó ń rí sí ọ̀ràn ìṣíwọ̀lú fún ẹjọ wọn.
- Tí wọ́n bá ti ṣètò sílẹ̀ fún ìgbẹ́jọ́ rẹ, wọ́n lè yí àkókò ìgbẹ́jọ́ padà sí ọjọ́ tó súnmọ́.

### Kí ni yóò ṣẹlẹ̀ tí mi ò bá lọ fún ìgbẹ́jọ́ ní ọjọ́ tí wọ́n ṣètò sílẹ̀?

- Wọ́n ti gbé àwọn ọjọ́ ìgbẹ́jọ́ àwọn mìíràn súnmọ́ tí wọ́n sì lè má lọ sí ilé-ẹjọ́ nítorí pé wọn kò mọ̀ pé ọjọ́ ti yí padà.
- Tí o kò bá lọ fún ìgbẹ́jọ́ àpapọ̀ olùjẹ́jọ́ rẹ, o máa gba àṣẹ ìyọkúrò. Èyí túmọ̀ sí pé wọ́n lè fi ọ́ sí àtìmọ́lé àti/tàbí le ọ kúrò nílùú.

### Báwo ni mo ṣe lè ṣàyẹ̀wò ọjọ́ ìgbẹ́jọ́ ìṣíwọ̀lú mi?

- Tí o bá ní ẹjọ́ ní ilé-ẹjọ́ tó ń rí sí ọ̀ràn ìṣíwọ̀lú, o lè wo ojú òpó wẹ́ẹ̀bu ètò ìsọfúnni ẹjọ́ aláìfọwọ́yí ti EOIR tàbí pe aago lóòrèkóòrè fún àwọn àyípadà èyíkéyìí nípa àwọn ọjọ́ ìgbẹ́jọ́.
- Láti wo ọjọ́ àti ibi ìgbẹ́jọ́ rẹ:
    - Ṣàyẹ̀wò sí acis.eoir.justice.gov kí o sì tẹ dígítì-9 A-number rẹ síi àti orílẹ̀-èdè tí o ti wá, tàbí
    - Pe 1-800-898-7180 kí o sì tẹ̀lé àwọn ìtọ́ni.

### Báwo ni mo ṣe lè dáàbò bo ara mi?

- Máa ṣàyẹ̀wò ọjọ́ ìgbẹ́jọ́ rẹ lóòrèkóòrè kí o má bá à pa ọjọ́ náà jẹ.
- Múra sílẹ̀ kí o sì ṣe ètò ààbò pẹ̀lú ẹbí tàbí àwọn ará àwùjọ rẹ bí ó bá ṣẹlẹ̀ pé wọ́n fi ọ́ sí àtìmọ́lé.
- Darapọ̀ mọ́ àwọn ìjọ ìtìlẹyìn ti ilé-ẹjọ́ tàbí ní ẹnìkan tí yóò tẹ̀lé ọ lọ fún ìgbẹ́jọ́ rẹ.
- Tí o bá ní àmúyẹ, rí i dájú pé o ti forúkọsílẹ̀ fún ètò ibi ìsádi tàbí fún àwọn ìbẹ̀wẹ̀ mìíràn pẹ̀lú Ilé-ẹjọ́.
- Tí wọ́n bá fi ọ́ sí àtìmọ́lé tí o sì ń bẹ̀rù láti padà sí orílẹ̀-èdè rẹ àti/tàbí orílẹ̀-èdè míràn, sọ èyí kedere fún ICE àti àwọn òṣìṣẹ́ tó ń rí sí ọ̀ràn ìṣíwọ̀lú èyíkéyìí.
- O sì tún lè pe Ọ́fîsì NYS fún Aago Ìpe Pàjáwìrì Àwọn Aráàlú Amẹ́ríkà Tuntun ní 1-800-566-7636 fún àwọn ìbéèrè àti àbá nípa ibi tí o ti lè gba ìmọ̀ràn nípa òfin ìṣíwọ̀lú.

### Mọ Awọn Ẹ̀tọ́ Rẹ ní Ilé-ẹjọ́

- O ni ẹ̀tọ́ láti kọ ìdásílẹ̀ tàbí ìyọkúrò ṣáájú kí adájọ́ tó ṣe ìpinnu rẹ̀.
- O lè béèrè pé kí agbẹjọ́rọ̀ ICE fi àlàyé rẹ̀ fún ìdásílẹ̀ tàbí ìyọkúrò ní àkọ́ọ́lẹ̀, kí o lè ní ààyè láti sàlàyé fún adájọ́ ìdí tí o fẹ́ fi tẹ̀síwájú pẹ̀lú ẹjọ́ rẹ àti láti béèrè fún ìrànlọ́wọ́ òfin.
- Tí adájọ́ bá fagilé ẹjọ́ rẹ tàbí tó pàṣẹ pé kí wọ́n yọ ọ́ kúrò ní ilé ẹjọ́, o lẹ́tọ̀ọ́ láti pe ẹjọ́ kòtẹ́milọ́rùn. O lè pe ẹjọ́ kòtẹ́milọ́rùn sí Ìgbìmọ̀ Tó Ń Rí Sí Ẹjọ́ Kòtẹ́milọ́rùn Lórí Ìṣíwọ̀lú (BIA). Ríi dájú pé o sọ fún adájọ́ ìṣíwọ̀lú pé o fẹ́ pe ẹjọ́ kòtẹ́milọ́rùn.
- Fún àwọn ìsọfúnni síwájú síi nípa àwọn ẹ̀tọ́ rẹ, ṣàyẹ̀wò sí nyic.org/kyr

# Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ

## Ìmúṣẹ Òfin Ìṣíwọ̀lú

### Kí ló ń ṣẹlẹ̀?

- Lábẹ́ Ìjọba Ààrẹ Trump, ìmúṣẹ òfin ìṣíwọ̀lú ti pọ̀ sí ní àwọn agbègbè wa.
- Àwọn òṣìṣẹ́ Àkóso Ìṣíwọ̀lú àti Gbígbófinró Àwọn Aṣọ́bodè (ICE) àti Àjọ Aṣọ́bodè àti Ààbò Ibodè (CBP) ti túbọ̀ jẹ́ kí àwọn ìgbóguntì àti ìfòfin mú ni wọn pọ̀ síi. Wọ́n sábà máa ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn agbófinró mìíràn, bíi àwọn ọlọ́pàá agbègbè àti òṣìṣẹ́ amúdàájọ́ṣe. Nítorí èyí, a ti rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn aráàlú tí wọ́n ti fi sí àtìmọ́lé àti ìgbésẹ̀ lílé kúrò nílùú.
- Àwọn tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ dé, àwọn èèyàn ti wọn kò ní ìwé, àwọn tí èdè àkọ́kọ́ wọn kìí ṣe Gẹ̀ẹ́sì, àti àwọn mìíràn lè wà ní ewu àwọn agbófinró.
- Jíròrò pẹ̀lú agbẹjọ́rọ̀ ìṣíwọ̀lú tí o bá ní àwọn ẹ̀dùn ọkan èyíkéyìí.

### Kí ni àwọn ẹ̀tọ́ mi tí ICE tàbí CBP bá dá mi dúró?

- Ó yẹ kí o mọ àwọn ẹ̀tọ́ rẹ nígbàkigbà tí o bá ń sọ̀rọ̀ pẹ̀lú Àkóso Ìṣíwọ̀lú àti Gbígbófinró Àwọn Aṣọ́bodè (ICE), Ẹ̀ṣọ́ Ibodè, tàbí àwọn agbófinró mìíràn.
- Tí agbófinró ìṣíwọ̀lú tàbí agbófinró mìíràn bá dá ọ dúró, rántí:
    - Farabalẹ̀. Má sáré. Má ṣe bá wọn fàjàngbọ̀n tàbí dí wọn lọ́nà.
    - Má parọ́ tàbí pèsè àwọn ìwé àkọsílẹ̀ èké.
    - O ní ẹ̀tọ́ láti dákẹ́ kí o sì má dáhùn àwọn ìbéèrè. O lè sọ pé, "Mo fẹ́ dákẹ́" tàbí "Mi ò fẹ́ dáhùn ìbéèrè."
    - Tí òṣìṣẹ́ kankan bá béèrè pé bóyá wọ́n le yẹ ara rẹ tàbí yẹ àwọn ẹrù rẹ wò, o ní ẹ̀tọ́ láti sọ pé, "Mi ò fọwọ́ sí àyẹ̀wò."
    - O ní ẹ̀tọ́ láti mọ̀ bóyá àti ìdí tí wọ́n fẹ́ fi fòfin mú ọ tàbí fi ọ́ sí àtìmọ́lé. O lè béèrè, "Ṣé mo lè máa lọ?" tàbí "Kí ni ìdí tí ẹ fi mú mi?"
    - O ní ẹ̀tọ́ láti ṣe ìgbàsílẹ̀ ohun tó ń ṣẹlẹ̀ sí ìwọ tàbí ẹlòmíràn. O lè sọ pé, "Mo ní ẹ̀tọ́ láti ṣe ìgbàsílẹ̀."
    - Tí agbófinró bá dá ọ dúró, fi ọ́ sí àtìmọ́lé, tàbí fòòró rẹ, gbìyànjú láti rí orúkọ, nọ́mbà, àti ìsọfúnni mìíràn tí a lè fi dá (àwọn) aṣojú náà mọ̀.
- Fún àwọn ìsọfúnni KYR ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ede, ṣàyẹ̀wò sí nyic.org/kyr

### Ṣé mo ní àwọn ẹ̀tọ́ àfikún bí ICE tàbí CBP bá wá sí ilé mi tàbí ibi iṣẹ́ mi?

- Ilé rẹ àti àwọn "ààyè aládàáni" (bíi agbègbè tó wà fún òṣìṣẹ́ nìkan ni ibiṣẹ́) ní àwọn ààbò àkànṣe tí àwọn ààyè àwùjọ kò ní.
- Àwọn ẹ̀ṣọ lè wọ àwọn ààyè àdáni nìkan pẹ̀lú ìyọ̀nda rẹ tàbí tí wọ́n bá fi àṣẹ ilé-ẹjọ́ hàn ọ, èyí tí adájọ́ buwọ́lù.
- Tí ICE bá wá sí ilé rẹ, o lè má ṣí ilẹ̀kùn rẹ rárá tàbí sọ pé, "Mi ò fọwọ́ sí àyẹ̀wò" àti kí o béèrè fún àṣẹ ilé-ẹjọ́.

### Àwọn Ìsọfúnni

Know Your Rights Wallet Card:

Know Your Rights Curriculum:

Know Your Rights with CBP:

Immigration Enforcement at the Workplace:

# Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ

## Ìmúṣẹ Òfin Ìṣíwọ̀lú

### Kí ni mo lè ṣe tí mo bá rí ICE tàbí CBP tó ń mú ẹnìkan tàbí ṣe ìgbóguntì?

- Tí o bá rí ICE tàbí CBP tó ń fòfin mú ẹnìkan, dákẹ́ jẹ́ẹ́ kí o sì rántí àwọn ẹ̀tọ́ rẹ.
- Fiyè sí aṣọ àti àwọn ọkọ̀ àwọn aṣojú náà, kí o sì ṣàkíyèsí àwọn ọ̀rọ̀ kankan tàbí àmì tó bá wà lára wọn.
- Tó bá dà bíi pé kò séwu fún ẹ, ṣe ìgbàsílẹ̀ fídíò tàbí ya àwòrán ohun tó ń ṣẹlẹ̀. O sì tún lè kọ ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ohun tó ń ṣẹlẹ̀.
  - Máa ṣọ́ra. Má ṣèdíwọ́ fún àwọn òṣìṣẹ́ náà.
- Tí ó bá yẹ bẹ́ẹ̀, pín ìsọfúnni nípa ìgbòkègbodò ìmúṣẹ òfin pẹ̀lú àwọn ẹ̀ka àjọ tí o fọkàn tán. Àwọn ọ̀pọ̀lọpọ̀ agbègbè ló ní aago ìpe pàjáwìrì tí o ti lè ṣe ìfisùn ìmúṣẹ òfin ìṣíwọ̀lú.
- Rí i dájú pé ìsọfúnni tí ó dájú nìkan ni o pín: nǹkan tí ìwọ tàbí ẹlòmíràn tí o gbẹ́kẹ̀lé rí. Rántí: òtítọ́, kìí ṣe ìbẹ̀rù!
- Pèsè àtìlẹ́yìn fún àwọn ẹni tàbí àwọn ìdílé ti ó kàn. Tí wọ́n bá fòfin mú tàbí fi ẹnìkan sí àtìmọ́lé, ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn ìjọ agbègbè tó ṣeé gbára lé láti ṣe àtìlẹ́yìn fún àwọn ẹbí àti aráalé wọn.
- Wá ìmọ̀ràn lọ sọ́dọ̀ agbẹjọ́rò ìṣíwọ̀lú tó o fọkàn tán.
- Fún àlàyé kan lórí ohun tí o máa ṣe tí o bá rí ICE tàbí CBP, ṣàyẹ̀wò sí nyic.org/kyr kí o sì ṣàwarí ìwé àkọsílẹ̀ yìí "Tí O Bá Rí Agbófinró Ìṣíwọ̀lú."

### Báwo ni mo ṣe lè múra sílẹ̀ fún bí ó bá ṣẹlẹ̀ pé wọ́n fi èmi tàbí ẹbí mi sí àtìmọ́lé?

- Tí ọ bá ti ń ṣe ọmọ ìlú U.S. tí ọ sì ní ọmọ, ọ gbọdọ̀ ṣètò sílẹ̀ tí ó bá wáyé pé ICE, CBP tàbí àwọn aṣojú ìjọba mìíràn bá fi ọ́ sí àtìmọ́lé.
- Láti gbáradì, ọ gbọdọ̀:
  - Tọ́jú àwọn ìwé àdéhùn pàtàkì sí ààyè tí kò léwu tí àwọn ará ẹbí rẹ mọ̀ nípa rẹ̀.
  - Pinnu lórí ẹni tí ìwọ yóò nífẹ̀ẹ́sí láti tọ́jú àwọn ọmọ rẹ ti ọ kò bá lánfààní láti mójútó wọn.
  - Yan ẹnìkan lábẹ́ òfin láti jẹ́ alábòójútó àwọn ọmọ rẹ.
    - Méjì nínú àwọn ọ̀nà tó wọ́pọ̀ láti yan alábòójútó lábẹ́ òfin ni;
      - Yíyan Ẹnìkan tó ní Ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Òbí
      - Alágbàtọ́ to wà Láròọ́wọ́tó
  - Fọwọ́sí àwọn àfikún fọ́ọ̀mù fún ọmọ rẹ, tó pẹ̀lú Fọ́ọ̀mù Ìwé-àṣẹ Ìrìn-àjò tàbí Fọ́ọ̀mù Olùkànsí Fún Pàjáwìrì ní Ilé-ìwé.
  - Ọ sì tún lè fẹ́ ronú nípa fífọwọ́sí fọ́ọ̀mù Fí Fa Ase lé Aṣojú Ẹni Lọ́wọ́.
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàyẹ̀wò sí nyic.org/kyr kí o sì ṣàwarí abala "Bí Ìdílé Ṣe Lè Múra Sílẹ̀".

### Àwọn Ìsọfúnni

If You See Immigration Enforcement:

Family Preparedness Guide:

Family Preparedness Forms:

# Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ

## Àtìmọ́lé Lórí Ọ̀ràn Ìṣíwọ̀lú

### Kí ni àwọn ẹ̀tọ́ mi tí wọ́n bá fi mi sí àtìmọ́lé?

- Rántí, o ní àwọn ẹ̀tọ́, kódà ní àtìmọ́lé!
  - O ní ẹ̀tọ́ láti dákẹ́ àti láti má dáhùn àwọn ìbéèrè.
  - O ní ẹ̀tọ́ láti bá agbẹjọ́rò sọ̀rọ̀, tàbí o lè gba àkókò rẹ láti wá ọ̀kan.
  - O ní ẹ̀tọ́ láti rí agbẹjọ́rò nígbà tí o bá wà ní àtìmọ́lé.
  - O ní ẹ̀tọ́ sí aago ìpe. O lè pe agbẹjọ́rò kan tàbí mọ̀lẹ́bí rẹ.
  - O ní ẹ̀tọ́ láti kàn sí ilé aṣojú ìjọba orílẹ̀-èdè rẹ.
  - O ò ní láti buwọ́lù ohunkóhun.

### Báwo ni mo ṣe lè ṣàwarí àtìmọ́lé tí wọ́n fi ẹnìkan sí?

- Láti ṣàwarí ẹni tó wà ní àhámọ́ ICE lọ́wọ́lọ́wọ́:
  - Lọ sí locator.ice.gov kí ọ sì tẹ:
    - Orúkọ, orílẹ̀-èdè ìbí, àti ọjọ́-ìbí ẹni náà tàbí
    - Dígítì-9 A-nọ́mbà
  - Olùṣàwarí ICE máa tọ́kasí ọgbà ìhámọ́ tí ẹni náà wà, ṣùgbọ́n ó lè gba àkókò díẹ̀ kí wọ́n tó farahàn lórí ètò yìí.
  - Tí ọ bá lérò pé èèyàn kan wà ní àtìmọ́lé ní ọgbà àhámọ́ ICE kan pàtó, ọ tún lè ní àǹfààní láti ṣàwarí wọn nípasẹ̀:
    - Wíwá wọn lórí accesscorrections.com. Tí orúkọ wọn bá hàn, Ó ṣeéṣe pé wọ́n wà ní àtìmọ́lé nínú ọgbà tí ọ tẹ orúkọ wọn sí.
    - Ọ lè kàn sí ọgbà náà tààrà ní ice.gov/detention-facilities
  - Tí ọ kò bá rí ẹni náà nípa lílo àwọn ètò orí ayélujára yìí, ọ lè kànsí ọ́fíìsì agbègbè Aláṣẹ ICE àti Iṣẹ́ Imúkúrò (ERO): ice.gov/contact/field-offices
  - Fún àlàyé síwájú sí lórí wíwá ẹnìkan tí a ti mú tàbí tí ó wà ní ìhámọ́ aṣíkiri, ṣàbẹ̀wò sí nilc.org/resources/how-to-find-a-loved-one-after-a-u-s-immigration-arrest/
    - Àwọn ohun èlò yìí wà ní àwọn èdè 9 pẹ̀lú Gẹ̀ẹ́sì, Arabic, Kannada, Haitian Creole, Korean, Tagalog, Vietnamese, àti Spanish.

### Kàn sí àwọn èèyàn nígbà tí o bá wà ní àtìmọ́lé ?

- Tí wọ́n bá bu owó béèlì tí èèyàn rẹ ò ní agbára láti san fun-un, wọ́n lè yẹ ní yíyan fún ìrànlọ́wọ́ owó béèlì ètò owó àkànlò fún béèlì
- Fún àlàyé síwájú síi lórí owó béèlì ní ìpínlẹ̀ New York, ṣàbẹ̀wò sí envisionfreedom.org/get-support
- Fún àtòjọ ètò ìrànlọ́wọ́ owó béèlì jákèjádò orílẹ̀-èdè, ṣàbẹ̀wò sí bit.ly/localbailfunds

### Àwọn Ìsọfúnni

Immigration Detention Support:

NILC's Guide "How to Find a Loved One after a U.S. Immigration Arrest":

# Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ

**Ilé-ẹjọ́ Ìṣíwọ̀lú**

## Báwo ni mo ṣe lè mọ̀ àti ìgbà tí mo bá ní ìgbẹ́jọ́ ní ilé-ẹjọ́ fún ọ̀ràn ìṣíwọ̀lú?

- Láti mọ ọjọ́ àti ibi ìgbẹ́jọ́ ẹnìkan:
  - Ṣàbẹ̀wò sí acis.eoir.justice.gov àti kí ọ sì tẹ dígítì-9 A-nọ́mbà ẹni náà, tàbí
  - Pe 1-800-898-7180 kí ọ sì tẹ̀lé àwọn ìtọ́nisọ́nà wọn.

## Ibo ni mo ti lè rí ìrànlọ́wọ́ nípa òfin?

- Láti rí ìsọfúnni àti ìtọ́ka ẹni sí fún ìrànlọ́wọ́ nípa òfin, pé Ọ́fìsì NYS fún Aago Ìpe Pàjáwìrì Àwọn Aráàlú Amẹ́ríkà Tuntun ní 1-800-566-7636.
- Àwọn olùgbé Ìlú New York náà le pe Aago Ìpe Pàjáwìrì Ìtìlẹ́yìn Òfin fún Ọ̀ràn Ìṣíwọ̀lú MOIA ní 1-800-354-0365, tàbí pe 311 kí o sì sọ pé “Òfin Ìṣíwọ̀lú.”
- Láti rí àtòjọ àwọn àjọ tí kìí ṣe fún ète ìṣòwò tó ń pèsè iṣẹ́ òfin lórí ìṣíwọ̀lú ní ọ̀fẹ́ tàbí lówó pọ́ọ̀kú káàkiri orílẹ̀-èdè, ṣàyẹ̀wò sí www.immigrationadvocates.org/legaldirectory
- Ṣọ́ra fún àwọn tó ń ṣe jìbìtì pẹ̀lú ìṣíwọ̀lú.
  - Òfin ìṣíwọ̀lú díjú. Máa ṣọ́ra nígbà tó o bá ń bá ẹnikẹ́ni tàbí ilé iṣẹ́ kan sọ̀rọ̀ nípa ipò tó o wà.
  - Agbẹjọ́rò tàbí aṣojú Ẹ̀ka Ètò Ìdájọ́ tí òfin fọwọ́ sí nìkan ló yẹ kí o bá sọ̀rọ̀ fún ìmọ̀ràn òfin lórí ipò rẹ.

## Báwo ni mo ṣe lè ṣe ìtìlẹ́yìn fún ẹnìkan tí ó ń gba ìdásílẹ̀ ní àtìmọ́lé?

- Owó àdéhùn jẹ́ owó tó jẹ́ sísan fún DHS láti ṣe ìdánilójú pé, tí ẹnìkan bá gba ìdásílẹ̀, wọ́n máa farahàn sí ilé-ẹjọ́ fún gbogbo ìgbẹ́jọ́ wọn.
- Tí wọ́n bá bu owó béèlì tí èèyàn rẹ ò ní agbára láti san fun-un, wọ́n lè yẹ ní yíyan fún ìrànlọ́wọ́ owó béèlì ètò owó àkànlò fún béèlì
- Fún àlàyé síwájú síi lórí owó béèlì ní ìpínlẹ̀ New York, ṣàbẹ̀wò sí envisionfreedom.org/get-support
- Fún àtòjọ ètò ìrànlọ́wọ́ owó béèlì jákèjádò orílẹ̀-èdè, ṣàbẹ̀wò sí bit.ly/localbailfunds

### Àwọn Ìsọfúnni

EOIR **Automated Case Information for Immigration Court:**

Immigrant Advocates Network Legal Directory:

Envision Freedom’s bond/ post-release resources:

# Ìlera

## Ìráyè sí ìbánigbófò ìlera

### Kí ni ètò ìbánigbófò ìlera àti ta ló ní àmúyẹ?

- Ìbánigbófò ìlera máa ń ran ni lọ́wọ́ láti sanwó fún ìtọ́jú ìṣègùn, bíi ìbẹ̀wò sí dókítà, ìdádúró sí ilé ìwòsàn, oògùn, àti àwọn pàjáwìrì. Ó lè mú kí ìtọ́jú ìṣègùn túbọ̀ rọrùn láti gbà ó sì máa dáàbò bò ọ lọ́wọ́ owó ìṣègùn tó ga.
- Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ló ní àmúyẹ fún ètò ìbánigbófò ìlera. O lè kúnjú ìwọ̀n fún oríṣi àwọn ètò tó dá lórí iṣẹ́ re, owó ọyà, ọjọ́ orí, àléébù ara, ipò ìṣíwọ̀lú, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Láti rí bóyá o ní àmúyẹ fún ìbánigbófò ìlera, ṣàyẹ̀wò sí: nystateofhealth.ny.gov

### Ǹjẹ́ àwọn olùṣíwọ̀lú tí wọn kò ní ìwé àṣẹ lè ní àmúyẹ fún ìbánigbófò ìlera?

- O lè ní àmúyẹ fún ìbánigbófò ìlera nítorí ọjọ́ orí àti/tàbí owó ọyà rẹ.
- Àwọn olùṣíwọ̀lú tí kò ní ìwé àṣẹ tí wọ́n ń gbé ní Ìpínlẹ̀ New York tí wọ́n jẹ́ ọmọ ọdún 65 àti jù bẹ́ẹ̀ lọ, tí owó ọyà kúnjú ìwọ̀n ohun kan pàtó tí wọ́n béèrè fún, ní àmúyẹ fún ètò Medicaid.
- Àwọn ọmọdé tí wọn ò ní ìwé àṣẹ tí wọn ò tíì tó ọmọ ọdún 19 ní àmúyẹ fún ètò Child Health Plus (CHP), l'éyì tó ń pèsè ìbánigbófò ìlera ọ̀fẹ́ tàbí oní owó pọ́ọ́kú lâì ka owó ọyà tàbí ipò ìṣíwọ̀lú wọn sí.

### Báwo ni mo ṣe lè forúkọsílẹ̀ fún ètò ìbánigbófò ìlera?

- Àwọn Aráàlú New York lè ní àǹfààní sí ètò ìbánigbófò ìlera ìjọba tàbí ti àwọn oní àfiṣòwò nípasẹ̀ Ẹ̀ka Ètò Ìlera Ìpínlẹ̀ New York.
  - Tí o bá yẹ fún ètò Medicaid, Ètò Kòṣeémáàní, tàbí Child Health Plus, ìforúkọsílẹ̀ wà ní ṣíṣí sílẹ̀ ní gbogbo ọdún.
  - Tí o bá gba ètò ìbánigbófò ìlera àfiṣòwò nípasẹ̀ ọjà ACA, àkókò ìforúkọsílẹ̀ tó ń bọ̀ yóò bẹ̀rẹ̀ láti 1 Oṣù Kọkànlá, 2026 – 15 Oṣù Kejìlá, 2026; èyí kúrú gan-an ju àwọn ọdún tó ti kọjá lọ..
    - Bí o bá kúnjú ìwọ̀n fún Àkókò Ìforúkọsílẹ̀ Àkànṣe, bíi lẹ́yìn àwọn ìyípadà nínú ipò ìṣíwọ̀lú, owó ọyà, ìṣípòpadà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ., ó lè ṣeé ṣe fún ọ láti forúkọsílẹ̀ kódà tí àkókò ìforúkọsílẹ̀ bá ti kọjá.
- Bí o ṣe lè forúkọsílẹ̀
  - Gba ìrànlọ́wọ́ ìforúkọsílẹ̀ ọ̀fẹ́ láti ọ̀dọ̀ Atọ́nà, fúnra rẹ̀ tàbí lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀. Wá Atọ́nà ní info.nystateofhealth.ny.gov/ipanavigatorsitelocations.
  - Pe Ibùdó Aṣojú Oníbàrà Ipò Ìlera NY ní 1-855-355-5777 (TTY: 1-800-662-1220).
  - Lórí ayélujára ní nystateofhealth.ny.gov. Ẹ̀yà Ìtàkurọ̀sọ kan wà lórí wẹ́búsáìtì lákòkò àwọn wákàtí ibùdó aṣojú oníbàrà láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọ fún píparí ìbẹ̀wẹ̀ rẹ.
  - Àwọn olùgbé Ìlú New York: pe 311, tẹ àtẹ̀jíṣẹ́ "CoveredNYC" sí 877-877, tàbí ṣàbẹ̀wò sí on.nyc.gov/healthinsurance fún ìrànlọ́wọ́ àti àfikún àwọn ohun èlò.
- Wá àlàyé ọlọ́pọ̀ èdè nípa ètò ìlera ní info.nystateofhealth.ny.gov/InformationalMaterials

### Àwọn Ìsọ̀fúnni

New York State of Health Website:

NYS Health Multilingual Resources:

# Ìlera

## Ìráyè sí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera

### Ǹjẹ́ àwọn iṣẹ́ ìpèsè wà fún àwọn èèyàn tí wọn kò ní ìbánigbófò ìlera?

- Kódà bí o kò bá ní àmúyẹ fún ìbánigbófò, o ṣì lè gba ìtọ́jú pàjáwìrì ó sì ṣeé ṣe kí o lè lọ sí àwọn ibùdó ìlera, ilé ìwòsàn, àti àwọn ètò ìlera agbègbè.
- Àwọn ilé ìwòsàn tí ìjọba àpapọ̀ fọwọ́ sí (FQHCs) gbọdọ̀ pèsè ìtọ́jú ìlera láì ka bóyá aláìsàn ní agbára láti sanwó, tàbí àìní ààbò ìbánigbófò wọn sí. Wọ́n máa ń ṣe ìdíyelé ní ìbámu pẹ̀lú owó ọyà tí wọn ò sì kí ń béèrè fún ẹ̀rí ipò ìṣíwọ̀lú.
  - Láti ṣàwarí ilé ìwòsàn kan tí ìjọba àpapọ̀ fọwọ́ sí nítòsí rẹ, ṣàyẹ̀wò sí findahealthcenter.hrsa.gov
- Àwọn ètò ìlera kan tún wà tí o lè lò láìní ìbánigbófò ìlera.
  - Àwọn Àyẹ̀wò Àrùn Jẹjẹrẹ:
    - Bí o kò bá ní ìbánigbófò, NYS ń pèsè àyẹ̀wò ọ̀fẹ́ fún àrùn jẹjẹrẹ ọmú, àpò ilé ọmọ, àti ìfun.
    - Fún àlàyé síwájú síi, ṣàyẹ̀wò sí health.ny.gov/diseases/cancer/services
- Àwọn Àjẹsára:
  - Bí o kò bá ní ìbánigbófò, Ètò Àjẹsára Ìpínlẹ̀ New York fún Àwọn Àgbàlagbà (VFA) ń pèsè àwọn àjẹsára láìsí idiyelé fún àwọn àgbàlagbà tó kúnjú ìwọn. Wọ́n máa ń pín àwọn àjẹsára náà fún àwọn ilé ìwòsàn tí wọ́n ti forúkọsílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí olùpèsè VFA.
  - Fún àlàyé síwájú síi, ṣàyẹ̀wò sí health.ny.gov/prevention/immunization
  - Fún àtòjọ àwọn àjẹsára ti a dábàá, ṣàyẹ̀wò sí bit.ly/vaccines26

### Kí ni àwọn iṣẹ́ tó wà fún àwọn olùgbé Ìlú New York?

- Ètò Ìtọ́jú NYC so àwọn olùgbé Ìlú New York papọ̀, láìka owó ọyà tàbí ipò ìṣíwọ̀lú wọn sí, pẹ̀lú ìráyè sí ètò ìlera Ìlú, Ìlera+Àwọn Ilé Ìwòsàn.
- Ètò Ìtọ́jú NYC kìí béèrè nípa ipò ìṣíwọ̀lú.
- O kúnjú ìwọn fún Ètò Ìtọ́jú NYC tí o bá:
  - Gbé ní Ìlú New York
  - O kò ní ìbánigbófò ìlera láti ọ̀dọ̀ agbanisíṣẹ́ rẹ
  - O kò kúnjú ìwọn fún ètò ìbánigbófò ìlera èyíkéyìí ní Ìpínlẹ̀ New York
  - Kò ní àmúyẹ fún ìbánigbófò ìlera ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ìtọ́ni ìjọba
- Bí o ṣe lè forúkọsílẹ̀:
  - Forúkọsílẹ̀ lórí fóònù: Pe 646-692-2273
  - Forúkọsílẹ̀ ní ojúkojú:
    - Ṣàbẹ̀wò sí ibi Ètò Ìlera NYC + Àwọn Ilé Ìwòsàn
    - Ṣàbẹ̀wò sí ìjọ agbègbè
    - Ṣàbẹ̀wò sí ọ́fíìsì MetroPlusHealth
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàyẹ̀wò sí nyccare.nyc

### Àwọn Ìsọfúnni

Find a federally qualified health center:

NYS Cancer Services:

NYS Vaccines:

NYC Cares:

# Ìlera

## Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ nínú ìtọ́jú ìlera

### Ṣé ICE lè gbé ìgbésẹ̀ ìmúṣẹ òfin tàbí fòfin mú ẹni ní ilé ìwòsàn?

- Ní Oṣù Kiní Ọdún 2025, ìjọba Trump fagilé ètò tó ti wà tipẹ́ tó pàṣẹ fún ICE àti CBP láti yẹra fún ṣíṣe ìmúṣẹ òfin ìṣíwọ̀lú ní "àwọn ààyè ẹlẹgẹ́" tàbí "àwọn agbègbè tó wà lábẹ́ ààbò " bíi àwọn ilé ìwòsàn. Èyí túmọ̀ sí pé àwọn ẹ̀ṣọ ICE le wọlé sí àwọn agbègbè inú ilé ìwòsàn níbi tí wọ́n á ti fàyè gba àwọn aráàlú lápapọ̀.
- Síbẹ̀síbẹ̀, Àtúnṣe Kẹrin Òfin ti Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà dáàbò bo ìpamọ́ gbogbo ènìyàn láìka ipò ìṣíwọ̀lú wọn sí. Púpọ̀ nínu àwọn ilé ìwòsàn ní àwọn agbègbè tí wọ́n jẹ́ àdáni tó sì ní ààbò lọ́wọ́ ìmúṣẹ òfin ìṣíwọ̀lú, àyàfi tí àwọn aṣojú náà bá ní ìwé àṣẹ ilé-ẹjọ́.

### Ǹjẹ́ àwọn ààbò NYS wà tó lè dènà wíwọlé ICE sínú ilé ìwòsàn láti fòfin mú ẹnìkan?

- Àwọn Aráàlú New York ní àwọn ààbò díẹ̀ ní àwọn ilé ìwòsàn.
- Àṣẹ Àkóso ti Ìpínlẹ̀ New York ti 2018 kan fòfin de ìmúṣẹ òfin ìṣíwọ̀lú ní àwọn ẹ̀ka iṣẹ́ ìpínlẹ̀ New York bíi àwọn ilé ìwòsàn ìpínlẹ̀, àyàfi tí ICE bá ní àṣẹ ilé-ẹjọ́.
- Lọ́jọ́ 27 Oṣù Karùn-ún, Ọdún 2026, Gómìnà Hochul àti Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣòfin Ìpínlẹ̀ New York gbé òfin tuntun kan kalẹ̀ tí wọ́n ń pè ní Ìlànà Ààbò fún Ibi Ẹlẹgẹ́, tó rangun sápá "àwọn ibi ẹlẹgẹ́" bíi kí ilé ìwòsàn le kọ ìwọlé àwọn agbófinró ìṣíwọ̀lú lái sí ìwé àṣẹ ilé-ẹjọ́.

### Kí ni a kà sí "àwọn ààyè àdáni" fún ilé ìwòsàn kan?

- Àwọn agbófinró, títí kan ICE àti CBP, ò leè ṣe àyẹ̀wò ní àwọn ibi tí a retí ìpamọ́ra tó bófin mu.
- Àwọn ẹ̀ka iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan yàtọ̀, sùgbọ́n a retí pé àwọn ọ́fíìsì dókítà tàbí àwọn yàrá àyẹ̀wò yóò wà lára ibi tí wọ́n kà sí "àwọn ààyè àdáni."
- Àwọn agbègbè bíi àyíká àbáwọlé tí ó wà ní ṣíṣí sílẹ̀ fún gbogbo ènìyàn kò ní kà sí "àdáni" nítorí náà wọn ò fi bẹ́ẹ̀ ní ààbò.

### Kí ni àwọn aláìsàn lè ṣe láti dáàbò bo ara wọn? Kí ni àwọn ilé ìwòsàn lè ṣe láti pa àwọn aláìsàn mọ́ nínú ewu?

- Láti dáàbò bo ara rẹ, àwọn aláìsàn lè:
  - Béèrè lọ́wọ́ ọ̀rẹ́ rẹ kan tàbí ẹnì kan ládùúgbò rẹ pé kó tẹ̀lé ọ lọ àti padà láti àwọn ìpàdé
  - Mọ àwọn ẹ̀tọ́ rẹ àti àwọn agbègbè wo ni àdáni àti èwo ni ti àwùjọ
  - Ṣètò kí o sì múra sílẹ̀ bí ó bá wáyé pé o ní ìbánisọ̀rọ̀ pẹ̀lú ICE tàbí CBP
- Láti pa àwọn aláìsàn wọn mọ́ nínú ewu, àwọn ilé ìwòsàn lè:
  - Tọ́ka sí ní í kedere kí o sì fi àwọn ààyè àdáni hàn
  - Ṣàgbékalẹ̀ àwọn ìlànà kedere fún ìbásọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn agbófinró, títí kan ICE àti CBP
  - Ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún gbogbo àwọn òṣìṣẹ́ lórí àwọn ẹ̀tọ́ wọn àti ojúṣe.
  - Ṣe ìtànkálẹ̀ àlàyé Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ ní àwọn oríṣiríṣi èdè káàkiri ilé ìwòsàn
  - Rántí àwọn ààbò ìpamọ́ ìkọ̀kọ̀ kí o sì má pín ìsọfúnni tó pọ̀ ju bó ṣe yẹ lọ pẹ̀lú àwọn agbófinró.
  - Fún àwọn àlàyé síwájú síi àti àbá, ṣàyẹ̀wò sí aclu.org/documents/immigration-enforcement-guidance-for-health-centers

**Àwọn Ìsọfúnni**

ACLU's "Immigration Enforcement Guidance for Health Centers"

# Àwọn ilé-ìwé àti ẹ̀kọ́

## Ìráyè sí ẹ̀kọ́

### Ta ni ó ní àmúyẹ láti lọ sí àwọn ilé ẹ̀kọ́ ìjọba NYS? Ṣé mo nílò láti ní ipò ìṣíwọ̀lú pàtó kan?

- Ìpínlẹ̀ New York ṣe ìdánilójú fún gbogbo ọmọdé, láìka ipò àwọn aṣíkiri sí, ẹ̀tọ́ sí ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ àti ojúlówó, tí ó bẹ̀rẹ̀ ní ilé-ìwé ògoweẹ̀rẹ àti títí tí wọ́n yóò fi gba ìwé-ẹ̀rí ilé-ẹ̀kọ́ gíga dípúlómà, tàbí kí wọ́n dàgbà ní òpin ọdún nínú èyí tí akẹ́kọ̀ọ́ náà yóò di ọmọ ọdún 21.
- Àwọn ilé-ẹ̀kọ́ ìjọba lè má béèrè nípa ipò ìṣíwá àti pé wọn kò ní pín àlàyé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ fún ètò ilé-ẹ̀kọ́ ojoojúmọ́ kankan. Àwọn ètò ìgbà èwe ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ pẹ̀lú wákàtí gígùn lè ní àwọn ìbéèrè ẹ̀tọ́ tó dá lórí owó-àpawọlé tàbí ìṣíwá.

### Báwo ni mo ṣe lè forúkọsílẹ̀ fún ilé ẹ̀kọ́ ìjọba?

- Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè béèrè àti forúkọ sílẹ̀ ní ilé-ẹ̀kọ́ ìjọba NYS nígbàkúùgbà yípo ọdún, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn àṣàyàn lè dínkù ní ìta àkókò ìforúkọsílẹ̀ ìbílẹ̀.
- Àlàyé Àwọn ilé-ìwé Ìjọba Ìlú New York
  - Fún àlàyé lórí ìlànà àwọn gbígbàwọlé ṣàbẹ̀wò sí schools.nyc.gov/enrollment/enrollment-help/new-students.
  - Láti wá àti béèrè wáyé sí Ilé-ìwé Ìjọba NYC, ṣàbẹ̀wò sí myschools.nyc, pe 311, tàbí ṣàbẹ̀wò sí Ibùdó Ìrànlọ́wọ́ Ìdílé kan. Àwọn agbègbè Ibùdó Ìrànlọ́wọ́ Ìdílé ni a lè rí ní schools.nyc.gov/fwc
  - Àkókò ìforúkọsílẹ̀ yàtọ̀ ní ìbámu pẹ̀lú oríṣiríṣi àwọn ìpele akẹ́kọ̀ọ́. Láti rí Àkókò Ìgbàwọlé Fall 2024, ṣàbẹ̀wò sí schools.nyc.gov/enroll.

### Àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wo ni àwọn ilé ẹ̀kọ́ béèrè fún láti ṣe ìforúkọsílẹ̀?

- Àwọn ilé ẹ̀kọ́ lè béèrè lọ́wọ́ àwọn ọmọ akẹ́kọ̀ọ́ àti òbí fún ẹ̀rí pé agbègbè ilé-ìwé náà ni ọmọ akẹ́kọ̀ọ́ ń gbé. Àwọn ìwé àkọsílẹ̀ lè pẹ̀lú ìwé ìyálé-gbé, àwọn ìwé ìsanwó ohunèlo ilé, fọ́ọ̀mù owó orí, tàbí ìwé ìdánimọ̀ kan.
- Àwọn iléèwé tún lè béèrè fún ẹ̀rí pé àgbàlagbà kan jẹ́ òbí tàbí alágbàtọ́ lábẹ́ òfin nínú àwọn ọ̀ràn mìíràn.
- Síbẹ̀síbẹ̀, àwọn ilé-ìwé ìjọba ìpínlẹ̀ New York kò leè béèrè pé kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tàbí àwọn òbí wọn pèsè nọ́mbà Ààbò Ìjọ tàbí àwọn ìsọfúnni mìíràn tí ó le tàbí kò ṣeé ṣe fún àwọn tí kìí ṣe ọmọ ìbílẹ̀, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí kò ní ìwé àṣẹ, tàbí àwọn ènìyàn tó gba ilé wọn láìní ìwé ìyálé-gbé láti fi hàn.

### Àwọn àsàyàn ẹ̀kọ́ wo ló wà fún àwọn àgbàlagbà akẹ́kọ̀ọ́?

- Ní NYS, o lè máa lọ sí ilé ẹ̀kọ́ ìjọba títí tí ìwọ yóò fi pé ọmọ ọdún 21 tàbí gba ìwé ẹ̀rí ìparí ilé ẹ̀kọ́ girama.
- Àwọn àsàyàn tún wà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àgbàlagbà tí wọ́n fẹ́ kọ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì tàbí gba GED.
- Láti ṣàwarí ètò ẹ̀kọ́ àgbà nítòsí rẹ, ṣàyẹ̀wò sí acces.nysed.gov/aepp/find-adult-education-program

### Àwọn Ìsọfúnni

NYC Public Schools Enrollment Information:

NYS Adult Education Programs:

# Àwọn ilé-ìwé àti ẹ̀kọ́

## Ìráyè sí ẹ̀kọ́

### Kí ló yẹ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti àwọn òbí ṣe bí wọ́n bá tàpá sí ẹ̀tọ́ wọn láti kẹ́kọ̀ọ́?

- Bí o bá rò pé ilé ẹ̀kọ́ kan tàbí iléèwé agbègbè kan ń gbìyànju láti dá ìforúkọsílẹ̀ ọmọ kan dúró nítorí ipò ìṣíwọ̀lú wọn, o lè kọ̀wé ìfisùn sí Amòfin Àgbà New York.
- Fún àlàyé síwájú síi àti ìráyè sí fọ́ọ̀mù ìfisùn, ṣàyẹ̀wò sí nysed.gov/data-privacy-security/parents-and-students-file-privacy-complaint

### Ṣé àwọn iléèwé ìjọba ń pèsè iṣẹ́ ìtumọ̀ èdè àti ògbufọ̀?

- Àwọn ìdílé ní ẹ̀tọ́ sí ìtúmọ̀ èdè àti ògbufọ̀ gbogbo àwọn ìwé àkọsílẹ̀ tó ní àlàyé pàtàkì nínú nípa ẹ̀kọ́ ọmọdé kan ní àkókò tó yẹ.
- Fún àlàyé lórí bí o ṣe lè béèrè fún àwọn iṣẹ́ ìtúmọ̀ èdè àti ògbufọ̀ ní Ilé Ẹ̀kọ́ Ìjọba NYC, ṣàyẹ̀wò sí schools.nyc.gov/hello tàbí pè ní 718-935-2013 tàbí 311.

### Ǹjẹ́ àwọn àsàyàn ìrànlọ́wọ́ owó wà láti jẹ́ kí lílọ kọ́lẹ́ẹ̀jì/ yunifásítì ò ní wọ́nwó?

- Bẹ́ẹ̀ni, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ètò ìrànlọ́wọ́ owó wà ní NYS.
- Ètò Ìrànlọ́wọ́ Owó Ìkẹ́kọ̀ọ́ (TAP) ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn olùgbé New York tí ó yẹ láti san owó ìkẹ́kọ̀ọ́ ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ tí a fọwọ́sí ní NYS.
  - Àmì-ẹ̀yẹ TAP ọdọọdún lè tó $5,665. Nítorí TAP jẹ́ ẹ̀bùn, a kò nílò láti san án padà.
  - Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti béèrè fún, ṣàbẹ̀wò sí hesc.ny.gov/tap
- Ẹ̀kọ́-ọ̀fẹ́ Excelsior
  - Ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ Excelsior, pẹ̀lú àpapọ̀ àwọn ètò ìrànlọ́wọ́ owó àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mìíràn, ń jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ sí kọ́lẹ́ẹ̀jì SUNY tàbí CUNY níbi tí wọn kì í sanwó ìkẹ́kọ̀ọ́.
  - Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti àwọn ìdílé tí owó-àpawọlé ọ́dọọdún wọn jẹ́ $125,000 tàbí kéré sí i ní ó ní ẹ̀tọ́ láti béèrè.
  - Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti béèrè fún, ṣàbẹ̀wò sí hesc.ny.gov/excelsior
- Aṣòfin José Peralta New York State DREAM Act fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mìíràn ní àǹfàní sí àwọn ẹ̀bùn àti ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ tí NYS ń ṣàkóso tí ó ń ṣe àtìlẹ́yìn fún iye owó ẹ̀kọ́ gíga wọn.
  - Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti béèrè fún, ṣàbẹ̀wò sí hesc.ny.gov/dream

### Àwọn Ìsọfúnni

NYSED Complaint Form:

NYC Schools Interpretation/ Translation Information:

Tuition Assistance Program Info:

Excelsior Scholarship Info:

DREAM Act Scholarship Info:

# Àwọn ilé-ìwé àti ẹ̀kọ́

## Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ ní àwọn ilé-ìwé

### Ṣé ICE lè gbé ìgbésẹ̀ ìmúṣẹ òfin tàbí fòfin mú ẹnìkan ní ilé ẹ̀kọ́ ìjọba NYS?

- Ní Oṣù Kiní Ọdún 2025, ìjọba Trump fagilé ètò tó ti wà tipẹ́ tó pàṣẹ fún ICE àti CBP láti yẹra fún ṣíṣe ìmúṣẹ òfin ìṣíwọ̀lú ní “àwọn ààyè ẹlẹgẹ́” tàbí “àwọn agbègbè tó wà lábẹ́ ààbò “ bíi àwọn ilé ẹ̀kọ́.
- Síbẹ̀síbẹ̀, Àtúnṣe Kẹrin Òfin ti Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà dáàbò bo ìpamọ́ gbogbo ènìyàn láìka ipò ìṣíwọ̀lú wọn sí. ICE àti àwọn aṣojú míràn ò leè wọ “àwọn ààyè àdáni” láìsí àṣẹ ilé-ẹjọ́ tàbí ìyọ̀nda oníhun. Púpọ̀ nínu àwọn ilé ẹ̀kọ́ ní àwọn agbègbè tí wọ́n jẹ́ àdáni tó sì ní ààbò lọ́wọ́ ìmúṣẹ òfin ìṣíwọ̀lú, àyàfi tí àwọn aṣojú náà bá ní ìwé àṣẹ ilé-ẹjọ́.

### Ǹjẹ́ àwọn ààbò NYS wà tó lè dènà wíwọlé ICE sínú ilé ẹ̀kọ́ láti fòfin mú ẹnìkan?

- Àwọn Aráàlú New York ní àwọn ààbò díẹ̀ ní àwọn ilé ìwòsàn.
- Àṣẹ Àkóso ti Ìpínlẹ̀ New York ti 2018 kan fòfin de ìmúṣẹ òfin ìṣíwọ̀lú ní àwọn ẹ̀ka iṣẹ́ ìpínlẹ̀ New York bíi àwọn ilé ẹ̀kọ́ ìjọba, àyàfi tí ICE bá ní àṣẹ ilé-ẹjọ́.
- Lọ́jọ́ 27 Oṣù Karùn-ún, Ọdún 2026, Gómìnà Hochul àti Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣòfin Ìpínlẹ̀ New York gbé òfin tuntun kan kalẹ̀ tí wọ́n ń pè ní Ìlànà Ààbò fún Ibi Ẹlẹgẹ́, tó rangun sápá “àwọn ibi ẹlẹgẹ́” bíi kí ilé ẹ̀kọ́ le kọ ìwọlé àwọn agbófinró ìṣíwọ̀lú láì sí ìwé àṣẹ ilé-ẹjọ́.

### Ṣé ICE lè fòfin mú ni tí àwọn ọmọ akẹ́kọ̀ọ́ bá ń lọ/ padà láti ilé ẹ̀kọ́?

- ICE lè, ní àwọn ọ̀ràn kan, fòfin mú ẹnìkan ní ìta gbangba, títí kan lójú pópó níbi tí àwọn ọmọ akẹ́kọ̀ọ́ ti ń rìnrìn àjò lọ tàbí padà láti ilé ẹ̀kọ́. Rìnrìn àjò lọ/ padà láti ilé ẹ̀kọ́ lè ní ewu jù bí àwọn ọmọ akẹ́kọ̀ọ́ ṣe ń rìn, dúró sí àwọn ibùdó ọkọ̀, tàbí rìnnà nínú àwọn ọkọ̀ àdáni.
- NYS ti ẹ̀ ní àwọn àkànṣe ààbò tó dènà àwọn asoju ICE láti wọlé sínú àwọn ọkọ̀ ilé-ìwé láì ní àṣẹ ilé-ẹjọ́.

### Báwo ni àwọn ọmọ akẹ́kọ̀ọ́ ṣe lè dáàbò bo ara wọn? Kí ni àwọn ilé ẹ̀kọ́ lè ṣe láti dáàbò bo àwọn ọmọ akẹ́kọ̀ọ́ wọn nínú ewu?

- Láti dáàbò bo ara rẹ, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè:
  - Béèrè lọ́wọ́ ọ̀rẹ́ rẹ kan tàbí ẹnì kan ládùúgbò rẹ pé kó tẹ̀lé ọ lọ àti padà láti ilé ẹ̀kọ́
  - Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ
  - Ṣètò kí o sì múra sílẹ̀ bí ó bá wáyé pé o ní ìbánisọ̀rọ̀ pẹ̀lú ICE tàbí CBP
- Láti pa àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọn mọ́ nínú ewu, àwọn ilé ẹ̀kọ́ lè:
  - Tọ́ka sí ní í kedere kí o sì fi àwọn ààyè àdáni hàn
  - Ṣàgbékalẹ̀ àwọn ìlànà kedere fún ìbásọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn agbófinró, títí kan ICE àti CBP
  - Ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún gbogbo àwọn òṣìṣẹ́ lórí àwọn ẹ̀tọ́ wọn àti ojúṣe.
  - Ṣe ìtànkálẹ̀ àlàyé Mọ Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ ní àwọn oríṣiríṣi èdè káàkiri ilé ìwòsàn
  - Rántí àwọn ààbò ìpamọ́ ìkọ̀kọ̀ kí o sì má pín ìsọfúnni tó pọ̀ ju bó ṣe yẹ lọ pẹ̀lú àwọn agbófinró.
  - Fún àwọn àlàyé síwájú síi àti àbá, ṣàyẹ̀wò sí aclu.org/documents/immigration-enforcement-guidance-for-health-centers

**Àwọn Ìsọfúnni**

ACLU’s “Immigration Enforcement Guidance for Schools”

# Ààbò Àgbègbè



**Gbogbo ènìyàn, láìka ipò ìwọlé tàbí ìdánimọ̀ sí, yẹ kí ó wà ní ààbò ní agbègbè wọn.**

### Ẹ̀ṣẹ̀ Ìkóríra àti Ẹ̀tanú

- Ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra jẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ tí ó jẹ́ ìwúrí nípasẹ̀ ẹ̀tanú sí ẹ̀yà ènìyàn, àwọ̀, ìpilẹ̀ṣẹ̀ orílẹ̀-èdè, ìdílé, ọkùnrin àti obìnrin, ẹ̀sìn, ìṣe ẹ̀sìn, ọjọ́ orí, àìlera tàbí ìbálòpọ̀.
- Ìpínlẹ̀ New York ní Agbófinró Ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra láti yanjú ìlọsíwájú nínú àwọn ìròyìn nípa ìdẹ́rùbà, ìnira àti ìwà ipá.
- Tí o bá rí ohun kan tàbí jẹ́ olùfaragbá ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra:
  - Sọ ọ́ fún Ìpín NYS ti Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn. Pe 1-888-392-3644, tẹ " HATE " sí 81336, tàbí lọ sí forms.ny.gov/s3/Hate-Crime-Tips. O lè ṣàbẹ̀wò sí dhr.ny.gov fún àlàyé síwájú síi
  - Láti ṣe ìjábọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra tí ó ń lọ lọ́wọ́ tàbí pàjáwìrì èyíkéyì, pe 911 lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀.
- Nígbà tí wọ́n bá ròyìn ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra, gbogbo àlàyé nípa ìrírí rẹ, ìdánimọ̀ rẹ, àti àwọn mìíràn ṣì wà ní ìkọ̀kọ̀.
- O lè ṣe ìjábọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra kí o sì gba àwọn iṣẹ́ láìka ipò ìwọlé rẹ sí.

### Àwọn Ohun Àmúlò Agbègbè

- Ọ́fíìsì Ìlú New York fún Ìdènà Ẹ̀ṣẹ̀ Ìkóríra ń pèsè àwọn iṣẹ́, àwọn ohun èlò, àti àtìlẹ́yìn fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè àti àjọ. Àwọn ohun èlò wà ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè. Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí nyc.gov/stophate.
- Ilé-iṣẹ́ fún Ẹ̀kọ́ Gbígbógun ti Ìwà Ipá ń ṣiṣẹ́ láti dènà, ṣe ìdíwọ́, àti láti wò ó sàn kúrò nínú ìwà ipá ìkóríra ní àwọn agbègbè New York. Wọ́n ní àwọn ètò ẹ̀kọ́ lórí ìdáàbòbò ara wọn, àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó wà nítòsí, àti agbára àwọn ọ̀dọ́. Pe 1-718-788-1775 tàbí ṣàbẹ̀wò sí caeny.org fún àlàyé síwájú síi.

### Sísopọ̀ pẹ̀lú Àgbègbè

- AAPI
  - Asian Americans for Equality: 212-979-8381, aafe.org
  - Chhaya for South-Asian and Indo-Caribbean communities: 718-478-3848, chhayacdc.org
  - Korean Family Service Center: 718-460-3800, kafsc.org
  - MinKwon Center for Community Action: 718-460-5600, minkwon.org
  - National Federation of Filipino American Associations New York: 212-684-0542, naffaa.org
  - Sikh Coalition: 516-930-0302, sikhcoalition.org
- Ará Áfíríkà
  - African Communities Together: 347-746-2281, africans.us
  - African Services Committee: 212-222-3882, africanservices.org
  - Sauti Yetu Center For African Women: 718-665-2486, sautiyetu.us
- Mùsùlùmí/Lárúbáwá
  - Arab American Association of New York: 718-745-3523, arabamericanny.org
  - Council on American-Islamic Relations of New York: 646-665-7599, cair-ny.org
  - Muslim Community Network: 347-519-2755, mcnny.org
- Àìpéra
  - Center for Disability Rights: 585-546-7510, cdrnys.org
  - Disability Rights New York: 518-432-7861, drny.org
- Hispanic/Latino
  - Hispanic Federation: 866-432-9832, hispanicfederation.org
  - Latino Commission on AIDS: 212-584-9325, latinoaids.org
  - Mixteca: 718-965-4795, mixteca.org
  - TransLatinx: 646-882-2000, translatinxnetwork.org
- LGBTQ+
  - Caribbean Equality Project: 347-709-3179, caribbeanequalityproject.org
  - Gay, Lesbian, Bisexual and Transgender Community Center: 212-620-7310, gaycenter.org
  - New York City Gay and Lesbian Anti-Violence Project: 212-714-1141, avp.org
- Abínibí Amẹ́ríkà àti Abínibí Alaska
  - American Indian Community House: 646-575-3638, aich.org
  - North American Indigenous Center of New York: 516-930-0302, naicny.org

# Àwọn ohun àmúlò iṣẹ́ NYS



### Ọ́fíìsì NYS fún Lílò Èdè

- Ọ́fíìsì NYS fún Lílò Èdè ń ṣàkóso àwọn iṣẹ́ lílò èdè fún mílíọ̀nù àwọn aráàlú New York tí wọn ò fi bẹ́ẹ̀ mọ èdè Gẹ̀ẹ́sì sọ dáadáa.
- Láti mọ àwọn ẹ̀tọ́ rẹ sí ògbufọ̀ àti àwọn iṣẹ́ ìtúmọ̀ èdè, ṣàbẹ̀wò sí ogs.ny.gov/know-your-rights
- Láti ṣe ìfisùn nípa lílò èdè, ṣàbẹ̀wò sí languageaccess.ny.gov/en-US.
- Láti gba àwọn ohun èlò tí a fi ń rí èdè lò tàbí láti béèrè àwọn ohun èlò tí a fi ń túmọ̀ èdè, fi ìbéèrè náà ránṣẹ́ sí àwọn àjọ alátìlẹyìn survey.alchemer.com/s3/8252338/OLA-Questionnaire

### Ọ́fíìsì NYS fún Ará Amẹ́ríkà tuntun

- Tí ìwọ tàbí ẹnìkan tí o mọ̀ bá nílò ìrànlọ́wọ́ òfin ọ̀fẹ́, pe ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀-ìyára náà ní 1-800-566-7636. Gbogbo àlàyé ìpè jẹ́ àṣírí. Ìrànlọ́wọ́ wà ní èdè 200+.

### Ẹ̀ka Ètò Ìlera NYS

- Béèrè fún Ìtọ́jú Ìlera: pe 1-855-355-5777 tàbí ṣàbẹ̀wò sí nystateofhealth.ny.gov.

### Ọ́fíìsì NYS fún Ìlera Ọpọlọ

- Fún àwọn ìbéèrè nípa àwọn iṣẹ́ ìlera ọpọlọ tàbí láti wá olùpèsè iṣẹ́ ìlera ọpọlọ, pe 1-800-597-8481 tàbí ṣàbẹ̀wò sí omh.ny.gov.
- Ìlà-ìpè ìyára Ìdènà Ìṣekúparaẹni Ìjọba àpapọ̀ : Tí ẹ̀mí rẹ tàbí ti ẹlòmíràn bá wà nínú ewu tó ń súnmọ́, pe 911. Tí o bá wà nínú wàhálà àti nílò ìrànlọ́wọ́ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, pe 1-800-273-8255 tàbí Tẹ "GOT5" sí 741-741.

### Ọ́fíìsì NYS fún Ìdènà ti Ìwà-ipá Ilé

- Tí ìwọ tàbí ẹlòmíràn bá wà nínú ìbáṣepọ̀ tí ẹlòmíràn ń ṣàkóso nípasẹ̀ ọ̀rọ̀, ti ara, tàbí ìlòkulò ìbálòpọ̀, tàbí àwọn ọgbọ́n míràn, pe Ẹ̀rọ Ìbánisọ̀rọ̀ NYS fún Ìwà Ipá Inú Ilé ní 1-800-942-6906.
- Láti bá agbẹjọ́rò sọ̀rọ̀ lórí ẹ̀rọ ayélujára, ṣàbẹ̀wò sí opdv.ny.gov. Ó wà ní 24/7 ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè.

### Ẹ̀ka Iṣẹ́ ti NYS

- Ẹ̀ka Iṣẹ́ ti ṣe ìpinnu láti dáàbò bo àti ìgbéga ààbò àti ìlera àwọn òṣìṣẹ́, owó oṣù, àti ipò iṣẹ́.
- Fún àlàyé nípa owó oṣù àti òfin wákàtí, ìlera ibi iṣẹ́ àti ààbò, tàbí láti fi ẹ̀sùn kan, pe 1-888-469-7365 tàbí ṣàbẹ̀wò sí dol.ny.gov/safety-and-health
- Fún ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú Ìdánilójú Àìríṣẹ́ṣe, pe 1-888-209-8124 tàbí ṣàbẹ̀wò sí dol.ny.gov/ unemployment/unemployment-insurance-assistance.

### Ìpín NYS ti Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn

- Òfin Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn ní New York fòfin de ìyàtọ̀ ní àwọn agbègbè bíi ìgbanisíṣẹ́, ilé, gbèsè, ẹ̀kọ́, àti àwọn ibi ìgbé gbogbogbò, tí ó dá lórí ọjọ́ orí, ẹ̀yà, ìpilẹ̀ṣẹ̀ orílẹ̀-èdè, ìbálòpọ̀, ìbálòpọ̀, ìdánimọ̀ ọkùnrin àti obìnrin tàbí ìfihàn, ipò ìgbéyàwó, àìlera, ipò ológun, àti àwọn ẹ̀ka mìíràn.
- Tí o bá rò pé wọ́n ti yà ọ́ sọ́tọ̀, fi ẹ̀sùn sílẹ̀ ní 1-888-392-3644 tàbí ṣàbẹ̀wò sí dhr.ny.gov.

### Ètò-Ilé NYS

- Fún ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú wíwá ilé tí kò wọ́n, pe 1-877-428-8844 tàbí ṣàbẹ̀wò sí nyhousingsearch.gov.
- Fún àlàyé lórí tẹ́tẹ́ ilé tí kò wọ́n ní ìlú New York, pe 212-863-7990 tàbí ṣàbẹ̀wò sí housingconnect.nyc.gov.
- Fún àlàyé lórí ẹ̀tọ́ àwọn ayálégbé ní Ìpínlẹ̀ New York, ṣàbẹ̀wò sí ag.ny.gov/publications/residential-tenants-rights-guide.

### Ọ́fíìsì NYS fún Àwọn iṣẹ́ Olùfaragbá

- Tí ìwọ tàbí ẹnìkan tí o mọ̀ bá ti ní ìrírí ìwà ìkórìra, Ọ́fíìsì NYS fún Àwọn iṣẹ́ Olùfaragbá lè ní àǹfàní láti ṣe ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú owó ìtọ́jú ìṣègùn àti ìnáwó ìmọ̀ràn, ìsìnkú àti iye owó ìsìnkú, owó oṣù tí ó sọnù, àti àwọn irúfẹ́ ìrànlọ́wọ́ mìíràn.
- Pe 1-800-247-8035 tàbí ṣàbẹ̀wò sí ovs.ny.gov fún àlàyé síwájú síi.

Láti wo ìwé yìí lórí ẹ̀rọ ayélujára tàbí ní àwọn èdè mìíràn, ṣàbẹ̀wò sí nyic.org/KYR tàbí ya àwòrán kóòdù yìí:

Tí o bá ní àwọn ìbéèrè tàbí àwọn àsọyé nípa irinṣẹ́ yìí tàbí àlàyé nínú rẹ, jọ̀wọ̀ kan si:
Bryan Lee – blee@nyic.org

Àgbáríjọ Àjọ Ìwọlé-jáde New York (NYIC) jẹ́ ìlànà àpapọ̀ àti àjọ alátìlẹ́yìn tí ó ń ṣojú fún àwọn ẹgbẹ́ aṣíkiri àti àwọn ẹgbẹ́ ẹ̀tọ́ àwọn aṣíkiri àti àwọn asásálà tó lé ní 200 káàkiri New York.

A fojú inú wo ìpínlẹ̀ New York tí ó lágbára nítorí pé gbogbo ènìyàn ni wọ́n gbà, tí wọ́n ń tọ́jú wọn dáadáa, tí wọ́n sì fún wọn ní àǹfàní láti lépa àlá wọn. Iṣẹ́ wa ni láti so àwọn aṣíkiri, àwọn ọmọ ẹgbẹ́, àti àwọn alájọṣepọ̀ pọ̀ kí gbogbo àwọn ará New York lè gbilẹ̀.

**New York Immigration Coalition**
131 W 33rd St, Ste 610
New York, NY 10001
212 627 2227
nyic.org